وَمَا هُوَ بِالْهَزْلِ ﴿١٤﴾

**14.** Atipe on ki işe ọ̀rọ̀ awadà.

إِنَّهُمْ يَكِيدُونَ كَيْدًا ﴿١٥﴾

**15.** Dajudaju nwọn nda ete lọna kan.

وَأَكِيدُ كَيْدًا ﴿١٦﴾

**16.** Emi nã si nwé-èwé lọna kan.

فَمَهِّلِ الْكَافِرِينَ أَمْهِلْهُمْ رُوَيْدًا ﴿١٧﴾

**17.** Nitorina dẹ awọn alaigbagbọ lẹkẹ ju wọn silẹ̀ fun igba diẹ.

## سُورَةُ الأَعْلَى

## *(87) Suratul - A'alã*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aşakẹ ọrun.*

سَبِّحِ اسْمَ رَبِّكَ الْأَعْلَى ﴿١﴾

**1.** Şe afọmọ orukọ Oluwa rẹ ti O ga julọ (A'lã).

الَّذِي خَلَقَ فَسَوَّىٰ ﴿٢﴾

**2.** Ẹniti O da ẹda ti O şe (e) dọgbadọgba.

وَالَّذِي قَدَّرَ فَهَدَىٰ ﴿٣﴾

**3.** Atipe O pebubu (ẹda) O si fi mọna.

وَالَّذِي أَخْرَجَ الْمَرْعَىٰ ﴿٤﴾

**4.** Atipe On ni Ẹniti O yọ koriko tutu jade.

فَجَعَلَهُ غُثَاءً أَحْوَىٰ ﴿٥﴾

**5.** O si sọ (koriko na) di gbigbẹ ti o dudu.

سَنُقْرِئُكَ فَلَا تَنسَىٰ ﴿٦﴾

**6.** Awa yio ke e fun ọ, ti irẹ kò fi ni gbagbe.

إِلَّا مَا شَاءَ اللَّهُ ۚ إِنَّهُ يَعْلَمُ الْجَهْرَ وَمَا يَخْفَىٰ ﴿٧﴾

**7.** Ayafi ohun ti Ọlọhun ba fẹ, dajudaju On ni O mọ ohun ti o han gbangba ati ohun ti o pamọ.

وَنُيَسِّرُكَ لِلْيُسْرَىٰ ﴿٨﴾

**8.** A o si şe ni irọrun fun ọ ọna ti o rọrun (awọn isẹ rere).

فذكر إن نفعت الذكرى ﴿٩﴾

**9.** Nitorina ki o mã şe işinileti, nigbati isinileti naa ba wulo.

سيذكر من يخشى ﴿١٠﴾

**10.** Ęniti o npaiya (Ọlọhun) yio ma tęti si i.

ويتجنبها الأشقى ﴿١١﴾

**11.** Bę si ni oloriburuku yio ma takete si i.

الذي يصلى النار الكبرى ﴿١٢﴾

**12.** Ęniti yio wọ ina ti o tobi.

ثم لا يموت فيها ولا يحيى ﴿١٣﴾

**13.** Lęhinna kò ni ku ninu rę bę si ni kò ni ję abęmi.

قد أفلح من تزكى ﴿١٤﴾

**14.** Dajudaju ęniti o ba şe mimọ́ ti jere.

وذكر اسم ربه فصلى ﴿١٥﴾

**15.** Ti o si nranti orukọ Oluwa (Ọba) rę̀ ti o si nkirun.

بل تؤثرون الحيوة الدنيا ﴿١٦﴾

**16.** Şugbọn aiye ni ę wà maiya.

والآخرة خير وأبقى ﴿١٧﴾

**17.** Bę si ni ọrun lo dara julọ ti yio si ma bę titi (şę kù).

إن هذا لفي الصحف الأولى ﴿١٨﴾

**18.** Dajudaju eyi mbę ninu awọn tirà ti akọkọ.

صحف إبراهيم وموسى ﴿١٩﴾

**19.** Tirà Ibrahima ati ti Musa.

## *(88) Suratul - Gãşiyah*

سورة الغاشية

بسم الله الرحمن الرحيم

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkę aiye, Aşakę ọrun.*

هل أتاك حديث الغاشية ﴿١﴾

**1.** Nję ọ̀rọ nipa ohun ti yio ma bo enia mọlę daru 'Gãşiyah' ti wa ba ọ?

وجوه يومئذ خاشعة ﴿٢﴾

**2.** Awọn oju kan yio dorikodo niti yẹ́pẹ́rẹ́ ni ọjọ na.